| ÀKỌLÉ | Ìdíyelé àti Gbígba àwọn Owó tí ó kù tíAláìsàn jẹ | | |
|---|---|---|---|
| NỌ́MBÀ | NH-LD-FM 111.5 | Àtúnṣe tó Kẹ̀hìn/Déètì Tí Àyẹ̀wò Bẹ̀rẹ̀: | Ọjọ kini, Oṣu kini, 2016 |
| ÀWỌN IṢẸ́ TJC | Ìtọjú ti Àtìrandéran | | |
| TỌ́KASÍ | Novant Health: Àwọn Ilé-ìwosàn, NHmg, Àwọn ilé iṣẹ́ Àwòrán Ìdádúró Àwọn Ilé Iṣẹ́ abẹ Ìdadúró, Àwọn Ilé iṣẹ́ Ìsọdọ̀tun, Onísòwò Caton Ilé, Ilé iṣẹ́ Àrùn-jẹjẹrẹ ti Ọmọọba William, Àwọn Ẹ̀ka Ilé-iṣẹ́ (NMG Àwọn Iṣẹ́ SouthPark – (CRNAs nìkan) | | |

## I. ỌNÀ / ÈRÈDÍ

Láti pèsè ìtọ́ni fún ìlànà ti ìdíyelé àti gbígba àwọn owó tí ó kù tí aláìsàn jẹ láàrin Novant Health.

Ọrọ ìlépa (“NH”) ti Novant Health, “ìmúgbóòrò ìlera àwọn àwùjọ ní ẹlẹ́ni kọọkan nígbà kan”n ṣàfihàn àṣà kììṣe-fún-èrè ti Novant Health àti ìjábọ̀ ojúlùmọ̀ ti àwon àwùjọ níbi tí a kalẹ sì. Èrèdí ti ìlànà yìí ni láti ṣàlàyé àkókò àfojúsùn àti ìgbésẹ̀ tí a fi béèrè ìsanpadà ní Novant Health tàbí ẹgbẹ́ mìíràn tó láṣẹ sí olùsanwó ẹgbẹ́ kẹta tàbí àwọn aláisàn.

## II. ÌLÀNÀ ÌṢE

A. Ìsanwó fún àwọn Iṣẹ́.

Ó jẹ́ ìlanà iṣẹ́ ti NH láti pèsè àwọn iṣẹ́ tí ójẹmọ́ ìṣegùn ti pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ tí ójẹmọ́ ìṣegùn kíákíá, pẹ̀lú àidínkù àwọn iṣẹ́ tí a nílò lábẹ́ ìlanà iṣẹ́ NH EMTALA, ní ìbámu, sí ẹnikẹ́ni láiní fiṣe ipá ènìyàn náà láti san tàbí yíyẹ fún ìranwọ́ owó lábẹ Ìlanà Iṣẹ́ Inú-rere ti Novant Health.

Fún àwọn aláìsàn tí kò sí lábẹ́ olùsan ẹgbẹ́ kẹta, ohun elò àti tàbí àgọ́-ìwosàn farajì láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú aláìsàn láti ri i dájú pé aláìsàn náà di àgbéyẹ̀wò fún yíyẹ lọ́dọ̀ ìjọba àpapọ̀, ìpínlẹ̀, tàbí ìbílẹ̀ yóòwù tàbí bóyá aláìsàn náà kúnjú òṣuwọ̀n fún ìtọjú inú-rere NH tàbí àwọn ètò ìrànwọ́ owó mìíràn tàbí àwujọ /àwọn ètò ẹgbẹ́ kẹta yòówù.

Fún àwọn aláìsàn tí ó wà lábẹ́ ààbò (àwọn) adójútòfò ẹgbẹ́ kẹta, ohun elò àti tàbí àgọ́-ìwosàn yóò pèsè akitiyan ìdíyelé àti ipá gbígbà ní àifákókò ṣòfò. NH yóò ṣàkójọ adójútòfò aláìsàn níwọ̀n-ìgbà tí NH ṣàdéhùn pẹ̀lú olùsanwó àti bí a bá pèsè ìròyìn tí ó yẹ ní àkókò iṣẹ́. Ojúṣe aláìsàn ni láti san abala owó tí wọ́n jẹ fún ohun elò ní àkókò iṣẹ́.

Bí àisanwó bá wáyé, Novant Health lè gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyìí: darí àṣùwọ̀n owó sí ilé-iṣẹ mìíràn fún gbígbà tàbí ìjábọ̀ nípa àṣùwọ̀n owó ajigbèsè sí ilé-iṣẹ́atọ́ka onígbèsè, ní ìbámu pẹ̀lú àgbékalẹ̀ inú Ìlànà iṣẹ́ yíì nìkan. Kò sí ìgbésẹ̀ òfin tàbí ti ìdájọ́ tí a ó gbè lòdì sí aláìsàn fún àisan owó, pẹ̀lú àiní ìdínkù gbígbésẹ̀ lé ohun ìní, àìfààyè gbani lóri ohun ìní, fífipá gba àṣùwọ̀n owó ilé-ìfówopámọ tàbí ohun ìní ẹni mìíràn, bíbẹ̀rẹ̀ ìgbésẹ̀ ará ilú, ìlọ́ṣọ̀ àwọn owó ọ̀yà tàbí fifipá òfin múni tàbí fífi sábẹ ìwé òfin ti àsopọ̀ ara. Síwáju sí i, Novant Health kìí sún síwájú tàbí kọ̀, tàbí bèèrè sísan ṣáájú ìpesè, ìtọjú ìṣègùn tóyẹ nítorí àisanwó kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ ti ìwé owó ẹ̀nìyàn kan níti ìpesè ìtọjú ìṣaajú tí ó wà lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣẹ́ Inú-rere ti Novant Health.

B. Àwọn Akitiyan tí ó Mógbọ́n wá láti Pinnu Yíyẹ fún Ìtọjú Iṣé Inú-rere.

NH àti/tàbí àwọn alágbàtà ẹgbẹ́ kẹ̀ta ti NH gbéṣẹ́ fún kò níí kópa ní Ìṣẹ Gbígbà Ju bí-o-ti-yẹ (“ECAs”) ṣáájú sísa àwọn ipá tí ó jọjú láti pinnu bóyá aláìsàn yẹ fún gbígba ìranwọ́ owó lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere ti Novant Health.

Lára àwọn akitiyan tí ó jọjú ni gbígbé ìgbésẹ̀ tí a là sílẹ̀ ní àwọn Abala II.B.1, II.B 2, II.B.3 ati IIB.4.

1. *Ṣáajú Bíbẹ̀rẹ̀ àwọn ECA*. Ó keéré tán ọ̀gbọ̀n ọjọ́ ṣáajú bíbẹ̀rẹ̀ àwọn ECA, tí ó lè má bẹ̀rẹ̀ ṣáajú ìparí ti Àkókò Ìfitoníletí, NH kò níí ṣe àwọn nnkan wọ̀nyí:

(a) Pèsè àkíyèsí kíkọ fún àwọn aláìsàn tí ó (1) ntọ́ka pé ìrànwọ́ owó lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere wà fún àwọn tí ó yẹ;(2)nṣàfihàn ECA ti NH nípinnu láti ṣàgbékalẹ̀ láti gba sísan owó; àti (3) nkọ ọjọ́ ìparí lẹ́hìn èyí tí wọ́n lè bẹ̀rẹ̀ (àwọn) ECA tí kò dín ní ọ̀gbọ̀n ọjọ́ lẹ́hìn déètì tí a pèsè àkíyèsí kíkọ; ÀTI
(b) Pèsè Ìsọniṣóki Èdè Ketekete fún àwọn aláìsàn pẹ̀lú ìfitoníletí kíkọ òkè yíì; ÀTI
(c) Ṣe akitiyan tí ó jọjú láti pè àkíyèsí aláìsàn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ẹnu nípa Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere rẹ̀ àti bí aláìsàn ṣe lè rí ìrànwọ́ nípa ìlanà ìfórukọsílẹ̀.

2. *Ìgbékalẹ̀ Ìbeerè fún ǹnkan tí Kò pé*. Bí aláìsàn kan bá ṣe àgbékalẹ̀ ìbeerè fún ǹnkan tí kò pé Lákókò Ìbeerè fún ǹnkan, Novant Health yóò ṣe àwọn nnkan wọ̀nyìí:

(a) Dá ECA yóòwù dúró láti gba owó sísan fún ìtọjú náà àti pé kò níí bẹ̀rẹ̀ tàbí gbé ìgbésẹ̀ si i lóri ìgbésẹ̀ ìṣaajú ECA títí NH yóò fi pinnu bóyá ẹni náà yẹ fún ìtọjú iṣé inú-rere; ATI
(b) Pèsè àfiyèsí kíkọ fún aláìsàn náà èyí tó nṣàpèjúwè ìròyìn àfikún àti/tàbí àkọsílẹ̀ tí ó yẹ lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere náà tàbí ìbéèrè tí a gbọ́dọ̀ fàkalẹ̀ láti parí ìbéèrè tí ó ní ìroyìn ìkànsíni, pẹ̀lú nọ́ńbà ẹ̀rọ ìbánisọrọ̀ àti ìbùgbé àfojurí, ti ibi-iṣẹ́ NH tabi ẹ̀ka tí ò lè pèsè ìroyìn nípa Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere tí ó sì lè pèsè ìrànwọ́ pẹ̀lú ìgbésẹ̀ ìbéèrè, tàbí bí NH kòbá pèsè ìrànwọ́ pẹ̀lú ìlanà ìbéèrè náà, ó kéére tán ilé-iṣé tí kò wá èrè tàbí ilé-iṣẹ́ ìjọba tí ò le pèsè irúfẹ́ ìrànwọ́ bẹ́ẹ́; ÀTI
(c) Bí bẹ̀ẹ̀kọ́ kí ó kúnjú òṣuwọ̀n Ìpele II.B.3 ti Ìlanà yìí bí a bá gba ìbéèrè kan tí a parí Lákókò Ìbéèrè.

3. *àgbékalẹ̀ Ìbeerè fún Ǹnkan Tópé*. Bí aláìsàn kan bá ṣe àgbékalẹ̀ ìbeerè fún ǹnkan tópé NíÀkókò Ìbeerè fún ǹnkan, NH yóò ṣe àwọn nnkan wọ̀nyìí:

(a) Dá ECA yóòwù dúró láti gba owó sísan fún ìtọjú náà àti pé kò níí bẹ̀rẹ̀ tàbí gbé ìgbésẹ̀ si i lóri ìgbésẹ̀ ìṣaajú ECA títí tí NH yóò fi pinnu bóyá ẹni náà yẹ fún ìtọjú iṣé inú-rere; ATI
(b) Ṣe ìpinnu bóyá aláìsàn náà yẹ fún ìrànwọ́ lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere yóò sì fi tó aláìsàn létí ní kíkọ nípa ìpinnu yíyẹ yíì, pẹ̀lú irufẹ́ ìrànwọ́ tí ó tọ́ sí aláìsàn náà, àti ohun tó ṣokùnfa ìpinnu yíì; ÀTI
(c) Bí aláìsàn náà bá yẹ fún ìrànwọ́, NH yóò san padà fún aláìsàn náà iyekíye owó tí ó ti san fún ìtọjú náà tí ó kọjá iye owó tí ó pinnu láti san lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere (iye owó tí ó kéré sí $5, tàbí irufẹ́ iye owó mìíràn tí a ṣàgbékalẹ̀ nípa ìfitoléti tàbí àtẹ̀jáde ìtọni míìràn nínu Ìkéde Ìpawówọlé Lábẹ́lé, kò nílò dídá padà); ÀTI
(d) NH yóò gbé gbogbo ìgbésẹ̀ tí ó wà láti ṣe ìdápadà èyíkèyí ECA (àyàfi títa gbesè) tí a gbé lódì sí aláìsàn láti gba owó sísan fún ìrànwọ́ lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere. Àpẹẹrẹ èyí yóò jẹ́ láti sàyọkúrò nínu ìjábọ̀ gbèsè aláìsàn tí kò tọ́ tí a fisun agbaṣẹ́ṣe ìjábọ̀ oníbárà tàbí àjọ ajúwe onígbèsè.

4. *Yíyẹ Ìgbẹ́kẹ̀lé Àidanilójú Ìtọjú Iṣẹ́-inú rere*. NH lé ṣe dédé pinnu pé aláìsàn yẹ fún ìtọjú ọ̀fẹ́ lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣẹ Inú-rere ní dídálé ìròyìn ti ẹgbẹ́ kẹ̀ta pèsè tàbí ìpinnu àtẹ̀yìnwá fún yíyẹ fún Ìtọjú Iṣẹ́-inú rere.

5. *Ọ̀pọ̀ Àwọn Abala Ìtọjú.* Bí NH bá ṣàkópọ̀ iye owó tí ó yẹ ní sísan tí aláìsàn kòí san fún ọ̀pọ̀ àwọn abala ìtọjú, ṣáájú ṣíṣe ECA láti gba owó-sísan fún iye owó NH yóò dúró títí di ọgọ́fà ọjọ́ lẹ́hìn tí ó ti pèsè ọ̀rọ̀ àkọsílẹ̀ ìwé iye owó sísan síwájú fún abala ìtọjú tí kò pẹ́ tí a kọ sínu àkópọ̀ náà.

6. *Yíyẹ Fún Ìrànwọ́-Ìṣègùn*. Bí, lákókò gbígba ìbéèrè tí ó pé fún ìranwọ́ owó lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere NH, RCS gbàgbọ́ pé aláìsàn lè yẹ fún Ìrànwọ́-Ìṣègùn, ìpinnu yíyẹ lábẹ Ìlanà Ìtọjú Iṣé Inú-rere NH la lè sún síwájú títí di ìgbà tí a parí tí a sì ṣe ìfisílẹ̀ ìbéèrè Ìrànwọ́-Ìṣègùn tí a sì ṣèpinnu yíyẹ aláìsàn fún Ìrànwọ́-Ìṣègùn.

7. *Ìpinnu Bóyá NH ti kúnjú òṣuwọ̀n Ìpele Akitiyan Tó Jọjú.* Ṣáajú kí Novant Health tó bẹ̀rẹ̀ ECA, Ìgbimọ̀ Ìṣákóso Ìpawówọ̀lé Ìgbàgbogbo NH, tàbí ẹni tí a yàn, yóò ṣe àgbéyẹ̀wò yóò sì ní àṣẹ ìkẹhìn fún pípinnu pé akitiyan tó jọjú ni a ti ṣe, tí ó bá Ìlanà yìí mu, láti pinnu bóyá ẹnìkan yẹ fún ìtọjú inú-rere àti bóyá a lè bẹ̀rẹ̀ ECA.

8. *Bíbá Ẹgbẹ́ Kẹ̀ta Ṣe*. Bí NH bá fi gbèsè ṣọwọ sí tàbí ta á fún ẹgbẹ́ kẹ̀ta ní Àkókò Ìbéèrè, NH gbọ́dọ̀ gba ìfẹnukò àkọsílẹ̀ láti ọwọ́ ẹgbẹ́ kẹ̀ta tí àwọn wọ̀nyí wà nínú rẹ̀: (i) ẹgbẹ́ náà yóò dẹ́kun láti lò ECA lòdì sí aláìsàn náà títí NH bá ti sa gbogbo akitiyan tó jọjú tí a ṣàgbékalẹ̀ ní Ìpele II.B. lókè; (ii) ẹgbẹ́ náà yóò dá ECA yòówù lòdì sí aláìsàn dúró bí aláìsàn náà bá àgbékalẹ̀ ìbéèrè níÀkókò Ìbéèrè; (iii) bí aláìsàn náà bá ṣe àgbékalẹ̀ ìbéèrè ní Àkòkò Ìbéèrè ti NH sì pinnu pé wọ́n yẹ fún ìrànwọ́ lábẹ́ Ìlanà Ìtọjú Inú-rere, ẹgbẹ́ náà yóò ṣe nnkan wọ̀nyìí lásìkò: a) tẹ̀lé àwọn ìgbésẹ̀ nínu ìfẹnukò náà láti ríi dájú pé eni náà kò san owó àti pé kò ní ojúṣe láti san owó fún ìtọjú lábẹ Ìlanà Ìtọjú Inú-rere; b) ngbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó jọjú láti san-padà ECA yóówù tí wọ́n gbé lòdì sí aláìsàn náà; àti c) gba ìfẹ́nukò àkọsílẹ̀ láti ọwọ́ alágbàṣe-iṣẹ́ tí wọ́n san gbèsè fún tàbí ta á fún pé alágbàṣe-iṣẹ́ tẹ̀lé àwọn àmúyẹ òkè yìí bákan náà.

C. Àwọn Àlàyé Ìwé iye owó.

Gbogbo àwọn àlàyé ìwé iye owó gbọ́dọ̀ ní ìfitoníletí kíkọ gbàgàdà tí ó npè àfiyèsí àti ìwifún àwọn aláìsàn nípa wíwá ìrànwọ́ owó lábẹ́ Ìlanà Ìtọjú Inú-rere NH àti kí ó ní nọ́ǹbà ìbánisọ̀rọ̀ ilé-iṣẹ́ NH tàbí ẹ̀ka tí ó lè pèsè ìròyìn nípa Ìlanà Ìtọjú Inú-rere àti ìlanà ìbéèrè, àti ojú-òpó ayé-lu-jára- (tàbí URL) níbi tí a ti lè rí àwọn ẹ̀dà Ìlanà Ìtọjú Inú-rere, fọ́ọ̀mù ìbéèrè àti ibi gbígba Ìṣọníṣókí Èdè Gbàgàdà gbà.

D. Àríyànjìyan Ìwé iye owó

Bí aláìsàn kan bá ní ìbéèrè nípa ìwé iye owó, kí aláìsàn ó pe nọ́ǹbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tí a kọ sára ìwé iye owó. Aláìsàn tàbí aṣojú rẹ̀ lè ṣàríyànjiyàn ìwé iye owó nípa pípèsè àkíyèsí ti àwọn ohun tí a njiyàn lé lórí náà àti ìdí fún àríyànjiyàn sí ibi iṣẹ́ láàrín ọjọ́ márundínlógójì sí déétì ìwé iye owó náà. Àkíyèsí ni a lè pèsè nípa pípe nọ́ǹbà ara ìwé iye owó náà. Àríyànjìyàn ni Akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ Sáà Ìpawówọ̀lé yóò yanjú láàrín ọjọ́ iṣẹ́ mẹ́rìnlà láti ọjọ́ àkíyèsí àríyànjiyàn náà tí a fúnni ní tàbí déètì láti ìbéèrè fún èyíkèyí àfikún ìròyìn tàbí kíkọsílẹ̀, èyí yóówù tí ó bá pẹ́ jùlọ.

Bí a kòbá yanjú àríyànjiyàn náà ní ìbámu pẹ̀lú ìtẹ́lọ́rùn aláìsàn, aláìsàn tàbí aṣojú rẹ̀ lè ṣe kòtẹ́mílọ́ruǹ nípa ìpesè àkíyèsí ti kòtẹ́milọ́rùn àti òkunfà kòtẹ́milọ́rùn fún ibi iṣẹ́

láàrín ọjọ́ márundínlógójì (35) láti déètì ìpínnu lẹ́tà. Kòtẹ́milọ́rùn náà ni Igbákèjì Ààrẹ Àkókò Ipawówọlé yóò yanjú láàrín ọjọ́ iṣẹ́ mẹ́rìnlá láti ọjọ́ àkíyèsí tí a fúnni ní kòtẹ́milọ́rùn náà tàbí déètì inú ìbéérè fún èyíkèyí àfikún ìròyìn tàbí kíkọsílẹ̀, èyíkèyí yóówù tí ó bá pẹ́ jùlọ.

Aláìsàn tàbí aṣojú rẹ̀ gbọ́dọ̀ lo gbogbo ọ̀nà fún ìlanà àríyànjiyàn àti kòtẹ́milọ́rùn fún gbogbo àwọn àríyànjiyàn ìwé owó sísan. Fífiranṣẹ́ ìwé sọ̀wé-dowó fún ìsan díẹ̀ nínú iye owó tí ó ní àríyànjiyàn pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ "ìsan pátápátá'' lóri sọ̀wé-dowó ránṣẹ́, láìlo ìlanà òkè yìí, kò níí jẹ́ ìtẹ́lọ́rùn fún iye owó tí ajẹ àti pé Novant Health ṣì lè béèrè fún owó sísan ní pipé.

Ìlànà yíì lè yatọ̀ nítorí ìbudò àbí olùpesè.

E. Bíbéérè Àfojúsun Ìdíyelé àti Àlàsílẹ̀ Àtòkọ ti Ìdíyelé.

Aláìsàn lè gba àkópọ̀ ti ìdíyelé fún ọgọ́rùn DRG tí a sábà ńlò jùlọ, ogún àwọn ìgbésẹ̀ ìyàwòrán aláìsàn tí o ńgbalé wá, àti ogún ) ìgbésẹ̀ aláìsàn tí ó ṣe iṣẹ́ abẹ tí ó ń gbalé wá tí ó gbajú-gbajà jùlọ. A lè ṣe ìbéérè ni kíkọ sílẹ̀, lórí ẹ̀rọ tàbí nípa í-méélì, a ó sì pèsè ìròyìn láàrín ọjọ́ iṣẹ́ mẹ́ta tí a ti gbà ìbéérè ìwé ọjà. Aláìsàn lè béérè nípa pípe nọ́ńbà tí a kọ sára ìwé owó sísan tàbí fífi í-méélì ránṣẹ́ sí àdírẹ́sì ara ìwé owó sísan aláìsàn.

Aláìsàn lè béérè àkọ́sílẹ̀ ohun tí yóò san tí ó nṣàlàyé ní èdè tí ó yéni fún ẹni tí kò kàwé irufẹ́ nípàtó ti ìsanwó tàbí ìdíyelé ti aláìsàn náà jẹ. Gbogbo ìwé owó sísan aláìsàn tí a kò sàtòkọ sílẹ̀ ní yóò ní ìfítonilétí fún aláìsàn fún ẹtọ́ láti bèèrè, lọ́fẹ̀, ìwé owó àlàsílẹ̀. Aláìsàn lè béérè àkọ́sílẹ̀ ohun tí yóòsan ní àkókò yóòwù láàrín ọdún mẹ́ta lẹ́hìn déètì ìfisílẹ̀ tàbí fún ìgbà pípẹ́ bíi ibi iṣẹ́ bá ti ní aláìsàn ní ojúṣe láti san owó inú ìwé náà.

F. Ibeere fun Isanpada.

Aláìsàn lè bèèrè nípa ìsanpadà/àsanlé nípa pípe nọ́ńbà tí a kọ sí ara ìwé owó sísan aláìsàn náà. Gbogbo àsanlé owó ní a ó dà padà fún aláìsàn náà láàrín ọjọ́ márùndínláádọ́ta tí a gba ìfitonilétí fún irufẹ́ àsanlé owó bẹ́ẹ̀.

G. Àwọn ẹ̀dà ti Ìlànà yíì.

Ẹ̀dà ti Ìlanà yíì lọ́fẹ̀ẹ́ ni a lè gbà nípa bíbéérè nípa pípe nọ́ńbà tí a kọ sí ara ìwé sísan owó aláìsàn, tàbí fífi í-méélì ránṣẹ́ sí àdírẹ́sì tí a kọ sára ìwé sísan owó aláìsàn náà. Àwọn ẹ̀dà ti Ìlanà yíì ni a lè ráàye sí ní ojú-òpó ayé-lu-jára Novant Health

H. Títẹ̀lé Òfin Tí Ó Wà Nílẹ̀.

Gbogbo ohun elò NH àti àwọn ọ́físì onísẹ̀gùn, bí ó ti yẹ, ni yóò bójútó gbèsè tí kò wà ní ìbámu pẹ̀lú sísan owó tí tọ́ àti àwọn òfin gbígbà owó ní ìpínlẹ̀ níbi tí ibi-iṣẹ́ tàbí ọ́físì náà wà, àti láìyọkúrò NCGS 131E-91, tí ó tọ̀nà.

**AWỌN IYỌKURO**. Ìlànà yíì wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ ti a ṣe ní gbogbo ibi-iṣẹ́ Novant Health àti àwọn iṣé ẹgbẹ́ onísẹ̀gùn Kò kan àwọn iṣé tí àwọn onísẹ̀gùn aládàni tàbí akọ́ṣẹ́mọ̀ṣẹ́ mííràn ṣe. Ìlànà yíì bákàn náá kò kan àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ṣe láàrín tàbí níta ilé-ìwosàn/ibi-iṣẹ́ lọ́wọ̀ àwọn onísẹ̀gùn tàbí àwọn olùpesè ìtọjú-ìlera mííràn ṣùgbọ́n kò pin sí àwọn Onísẹ̀gùn Akunnilórun, Onísẹ̀gùn tí o ńlo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣàwarí ààrùn , àti/tàbí Onísẹ̀gùn tó ṣàwarí òkunfà àti ìdàgbà aarùn.

## III. ÒṢÌṢẸ́ AKỌ́ṢẸ-MỌṢẸ́

Òṣìṣẹ́ Iṣẹ́ Àkókò Ìpawówọlé

## IV. IRIN IṢẸ́

N/A

## V. ÌLÀNÀ

*Ìlànà náà wà gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ni láti ran òṣìṣẹ́ lọ́wọ́ ní dídé àwọn ìlépa ti ìlanà iṣẹ́ náà. Nígbà tí a bá ntẹ̀lé àwọn ìlànà ìtọ́ni yìí. òṣìṣẹ́ ní a lérò pé yóò ṣe ìdajọ́ ní ìbámu pẹ̀lú abala iṣẹ́ àti/tàbí ojúṣe iṣẹ́.*

## VI. ÀKỌSÍLẸ̀

N/A

## VII. ÀWỌN ÌTUMỌ̀

Àkókò Ìbéèrè – Àkókò tí o bẹ̀rẹ̀ ni déètì tí a ṣe ìtọjú náà àti ìgbà tí ó parí lẹ́hìn òjìlérúgba ọjọ lẹ́hìn déètì tí àkọsílẹ̀ ìwé sísan owó fún ìfisílẹ̀ ìṣaajú fún ìpesè ìtọjú TÀBÍ ní tí Novant Health pàkíyèsí aláìsàn sí gbígbé kalẹ̀ Ìṣe Gbígba Àrà-ọtọ̀, ọjọ́ ìparí tí a kọ sínu irúfẹ̀ ìfitoníletí bẹ́è tí a kọ sílẹ̀.

Ìtọjú Inú-rere – Aláìsàn tí kò ní ààbò tí owó oṣù rẹ̀ kéré tí ó yẹ fún àgbéyẹ̀wò Ìtọjú Inú-rere tí ó dá lórí níní àmúyẹ tí ó wà nínu Ìlanà Ìtọjú Inú-rere NH.

Ìṣe Gbígba Àrà òtò - èyíkèyí ojúṣe ti ibi-iṣẹ́ ìṣègùn gbé lòdì sí ẹnikẹ́ni ní ìbámu pẹ̀lú owó sísan ti ìwé owó sísan fún ìtọjú lábẹ ìlànà ìtọjú inú-rere ibi-iṣẹ́ ìṣègùn tí o nílò ìlanà òfin tàbí ti ìdájọ́, tí o ní iṣe pẹ̀lú títa gbèsè ẹni fún ẹlòmíràn, ìṣafisùn ìròyìn tí kò tọ́ nípa ẹni náà fún àwọn ilé iṣẹ́ ajúwe onígbèsè tàbí ibiṣẹ́ gbesè, tàbí yíyẹ tàbí sísẹ, tàbí nílò sísan owó ṣáajú ìpesè, ìtọjú ìṣègùn nítorí pé ẹnìkan kò san owó tàbí àfikún ìwé owó sísan fún àwọn ìtọjú tí a ti pèsè tẹ́lẹ̀ lábẹ́ ìlanà ìtọjú inú-rere ibi-iṣẹ́ ìṣègùn. Èyí kò pẹ̀lú èyíkèyí gbígbà ohun ẹni ti Novant Health lẹ́tọ̀ọ́ sí láti ṣe lábẹ òfin ìpínlẹ̀ lórí ìlanà ti ìdajọ́, ìyanjú tàbí àdéhùn tí ó jẹ́ aláìsàn (tàbí aṣojú rẹ̀) nítorí àwọn ìpálára ẹni tí ó wáyé fún èyí tí ilé-ìwosàn náà pèsè ìtọjú.

Ẹbí – Lára rẹ̀ ni ọkọ, ìyàwó, àti àwọn ọmọ yóòwú (pẹ̀lú àwọn ọmọ-ọkọ/ìyàwó ) tí o ń gbé nínu ilé náà tí o sì yẹ fún dídín owó orí kù

Owó to ń wọlé - Owó tí ẹbí ń pa wọlé lọ́dún àti àwọn ànfààní owó láti gbogbo orísun ṣáajú àwọn owó orí, yàtọ̀ sí owó fún owó ìtọjú obìrin tí a kọ sílẹ̀ àti àtìlẹ́hìn ọmọ. Ẹ̀rí owó tí o ń wọlé ni a lè pinnu nípa ṣíṣeàyẹ̀wò ibi yíya kúrò ìwé W-2, ìròyìn owó orí, tàbí àwọn ìwé àkọsílè míìràn tí o yẹ láti pinnu ìpò inú-rere ẹni.

Aláìsàn nílé Ìwosàn - Ẹni tí a gbà sí ibi-iṣẹ́ Novant Health fún àwọn iṣẹ́, aláìsàn sábà maa ńdúró ju wákàtí mẹ́rinlélógún lọ.

Ọ̀rọ̀ Ìṣègùn Pàjáwìrì – Àìròtẹ́lẹ̀ àsúyọ ìdúnkokò mọ́ ẹ̀mí tàbí ipò àìléra èyí tí ó jẹ́ pé bí à kó ba tọ́ju yóò ṣokunfà àìpéye tàbí pípàdánù ẹ̀mí tàbí ọwọ́.

[1Ọ̀rọ̀ Ìṣègùn Kíákíá - ÌtọjúÌṣègùn tí kò ìdúnkokò mọ́ ẹ̀mí ṣùgbọ́n tí a rí ní yíyẹ, pọn dandan, àti/tàbí tó yẹ, tí o dá lórí àrídìmú ẹ̀rí ìtọjú tó péye ti ìṣegùn.

Àkókò Ìfitoníletí - Àkókò tí o bẹ̀rẹ̀ ní déètì ìtọjú àkọkọ́ àti pípari ni ọgọ́fa ọjọ́ lẹ́hìn àkọsílẹ̀ sísan owó ìfisílẹ̀ tó kẹ́hìn èyí tí a ṣe ìtọjú fún.

NHMG - Ẹgbẹ́ Ìṣègùn Novant Health

Ìṣàyẹwò - Ìsọ̀rí aláìsàn tí o ńgba ilé wá sí ilé ìwosàn tí ó nfàyè gba aláìsàn láti dúró ní ibi-iṣẹ́ Novant Health títí di wákàtí mẹ́rìnlélógún láìmu u lọ sí ìpele aláìsàn tí ó dúró nílé ìwosàn.

Aláìsàn tí o ńgba ilé wá sí ilé ìwosàn - Ẹni tí o ńgba àbojutó/ìtọjú ní ibi-iṣẹ́ Novant Health tí o sì ńpadà lọ silé ní déètì iṣẹ́ kanná.

Ìsọníṣokí Èdè Ketekete - Gbólóhùn tí a kọ sílẹ̀ tí o ń pàkíyèsí ẹnikan sí i pe ibi-iṣẹ́ Novant Health ńpèsè ìrànwọ́ owó lábẹ Ìlànà Ìtọjú Inú-rere tí ó sì npèsè àwọn ìròyìn àfikún ní èdè tí ó já geere, ṣókí, àti rorùn láti yéni: (i) ìsọnìṣókí àpejúwè ti àwọn àmúyẹ ti ìrànwọ́ tí a ńfúnni lábẹ Ìlanà Ìtọjú Inú-rere, (ii) ìsọníṣókí bí a ti ńbèèrè fún ìrànwọ́ lábẹ Ìlànà Ìtọjú Inú-rere; (iii) ọgangan àdírẹ̀sì ojú-òpó ayé-lu-jára (tàbí URL) àti ibi ìkalẹ̀sì níbi tí ènìyàn ti lè gba àwọn ẹ̀dà ti Ìlanà Itọjú Inú-rere àti fọ́ọ̀mù ìbéèrè; (iv) àwọn ìtọ́ni bí oníkálukú ṣe le gba ẹ̀dà ti Ìlanà Ìtọjú Inú-rere àti fọ́ọ̀mù ìbéérè lọ́fẹ̀ẹ́; (v) àlàyé ìkansí, pẹ̀lú nọ́ńbà ẹ̀rọ̀ ìbánisọ̀rọ̀ àti ibi ìkalẹ̀sí, ti ibi iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka tí o lè pesè àlàyé nípa Ìlanà Ìtọjú Inú-rere àti bóyá ibi-iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka tí o lè pesè ìranwọ́ fún ìbéérè tàbí ibi-iṣẹ́ tí kìí ṣe fún èrè tàbí ilé-iṣẹ́ ìjọba tí ó lè pèsè ìrànwọ́; (vi) àlàyé lóri wíwá àwon ìtumọ̀ Ìlanà Ìtọjú Inú-rere, ìbéérè àti Ìsọníṣókí Èdè Kétekète ní àwọn èdè míìràn, bí ó bá wà, àti (vii) àlàyé pé ẹni tí ó yẹ fún Ìtọjú Inú-rere ni lè má san jù iye owó tí àwọn tí ó ní ìdójútòfò ńsan tí ó ní ìtọjú pàjáwìrì kanná tàbí ìtọjú ìṣègún míìrán tí ó yẹ.

RCS – Àwọn Àkókò Ìpawówọlé

## VIII. ÀWỌN ÌWÉ ÀDÉHÙN TÍ Ó JỌRA WỌN

- Ìbéèrè fún gbígba; Lẹ́tà Oníṣègùn; Ìyanjú Ìjàmbá; Ẹ̀dínwó Àìní-ìdábòbò; Ìlanà Sísan; Ìgbawọlé; Àwọn sísan àti Ìmọ̀ràn Ètò Ìnáwó
- Ìtọjú Inú-rere NH-Ẹ̀ka-FIN-BCD-111.1 v.2

## IX. ÀWỌN ÌTỌ́KASÍ

N/A

**X. A GBÉ E KALẸ̀ LÁTI ỌWỌ́**

Ìsan owo Novant Health àti Gbígbà ti Ẹ̀ka-Ìgbimọ̀ Àsankù Owó Aláìsàn

**XI. ÀWỌN KÓKÓ Ọ̀RỌ̀**

Sísan owó, Ńgbà, Gbígbà, Àsankù Owó Aláìsàn, Ìlé-kúrò, Gbèsè Àìlèsan, Ẹ̀tọ́ Adójútòfò, Lílé, Sísan owó, Gbèsè Àìlesan, Ìdíyelé

**XII.**

| | |
|---|---|
| **DÉÈTÌ TÍ O KỌ́KỌ́ BẸ̀Ẹ̀RẸ̀** | 08/2014 |
| **DÉÈTÌ TÍ ÀWỌN ÀTÚNṢE BẸ̀RẸ̀** | 01/01/2016 |
| **DÉÈTÌ ÀTÚNYẸ̀WÒ (Kò sí àyípàdà)** | |
| **Deeti Ti o Yẹ fun Atunyẹwo** | 01/2019 |

**ÌWÉ ÌBỌWỌ́LÙ**

| | |
|---|---|
| **ÀKỌLÉ** | Sísan Owó àti Gbígba Àsankù Owó Aláìsàn |
| **NỌ́ŃBÀ** | NH-LD-FM-111.5 |
| **TJC ÀWỌN IṢÉ** | Ìtọjú àtirandéran |
| **Ó BÀ A WÍ** | Àkókò Ìpawówọlé Novant Health |
| **ÌṢE** | Ìbẹrẹ̀ |

**TÍ A FỌWỌSÍ NÍPASẸ:**

| **Àkọlé** | **Tí a fọwọsí Nípasẹ̀** | **Ìbọwọ́lù** | **Déètì** |
|---|---|---|---|
| SVP, Àkókò Ìpawówọlé | Richelle Menke Fleischer | | Wo ìbọwọ́lù orí ẹ̀rọ |
| | | | |
| | | | |

**A FI ỌWỌ́ SÍ ÀWỌN ÌGBIMỌ̀ NÍPASẸ̀**

| **Ìgbimọ̀** | **Alága/Aṣojú** | **Déétì** |
|---|---|---|
| NHMG Àwọn Ọ̀ṣùwọ̀n Àgọ́-ìwosàn /Ìgbimọ̀ Aláábò Aláìsàn | John Card, MD, Alága | |
| | | |